# ÈRÈ IGBAGBỌ́ ATI IFORITI

## Matteu 15:21-31; Marku 7:31-37

### Ẹ̀KỌ 96 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Igbagbọ́ nla ni tirẹ: ki o ri fun ọ gẹgẹ bi iwọ ti nfẹ" (Matteu 15:28).**

**Bibeere fun Iranlọwọ**

Jesu lọ si Sidoni ati Tire, awọn ilu buburu wọnni, nibi ti obinrin kan tọ Ọ wá, ti o si n beere fun iranlọwọ. Oun ki i ṣe Ọmọ Israẹli ṣugbọn ọ̀kan ninu awọn Keferi ni oun i ṣe, nigba miiran a maa n pè é ni obinrin ara Sirofenikia nitori ilu Fenikia ni Siria ni ó n gbé. Ọlọrun rán Jesu si awọn Ọmọ Israẹli tabi awọn Ju, awọn ayanfẹ Ọlọrun. Nigba ti Jesu rán awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ jade, aṣẹ ti O fun wọn ni lati waasu fun awọn Ju, ki i ṣe fun awọn Keferi (Matteu 10:5, 6). Lẹyin naa, awọn ọmọ-ẹyin waasu fun awọn Keferi, pẹlu (Iṣe Awọn Aposteli 15:7), nitori Jesu ti tọ awọn ti Rẹ̀ wá, ṣugbọn wọn kò gbà Á (Johannu 1:11).

Boya obinrin yii ti gbọ nipa ọpọlọpọ awọn eniyan ti Jesu ti wosan. O ni igbagbọ pe Jesu le wo ọmọbinrin oun ti o n ṣaisan lọpọlọpọ sàn. A ko sọ fun wa pato iru arun tabi irora ti eṣu fi si ara ọmọbinrin yii, ṣugbọn eyi ko ja mọ nnkan kan. Jesu lagbara lati wo gbogbo arun sàn. Ko si arun tabi aisan, bi o ti wu ki o buru to, ti o le ko Ẹjẹ Jesu loju.

**Kò si Ọrọ Iwuri**

Obinrin yii kigbe pe Jesu fun aanu. Awọn ọmọ-ẹyin gbiyanju lati pa a lẹnu mọ nitori ki i ṣe Ju. Boya ó ro pe Jesu kò gbọ́ igbe oun, nigba ti Oun ko dahun lesẹkẹsẹ. Nipa ṣiṣe bayii, O n dán igbagbọ́ rẹ̀ wò. Awọn miiran i ba ti ro pe idakẹ yii fihàn pe a dù ú ni ibeere rẹ̀, ṣugbọn eyi ko tete mu irẹwẹsi ba a. Nikẹyin Jesu wi fun un pe a rá n Oun si ile Israẹli, awọn Ju. Sibẹ o tẹra mọ ọn, o si tun beere. O gba pe Jesu ni Messia, tabi Ẹni ti a ti ṣeleri fun awọn Ju, nitori ó pe E ni "ọmọ Dafidi." O gbagbọ pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu I ṣe, Ẹni ti a rán bi Olugbala (Luku 2:11; Johannu 3:16).

Adura rẹ̀ ko gùn, ṣugbọn o yanju, nitori o sọ aini rẹ̀ o si sọ ohun ti oun n fẹ fun Un. O wolẹ fun Un, o si wi pe, "Oluwa, ràn mi lọwọ." Ọlọrun maa n gbọ adura kukuru gẹgẹ bi O ti n gbọ adura gigun. Ọna ti ó fi gbadura ni o mu ki ọkàn Olugbala gbọgbẹ́. Adura rẹ̀ ni, "Ràn Mi lọwọ." O mọ aini ara Rẹ̀; nigba ti Jesu n wo awọn miiran sàn, ko fẹ ki O kọja lara oun ati ọmọbinrin rẹ̀.

**Adura Ẹlẹṣẹ**

Ọpọlọpọ ẹlẹṣẹ ti ri igbala nigba ti wọn gbadura gẹgẹ bi obinrin yii. Awọn miiran ko sọ ju ohun ti obinrin yii sọ, ṣugbọn wọn wá pẹlu ẹmi ironupiwada. Wọn mọ pe wọn n fẹ iranlọwọ ati pe Ọlọrun nikan ṣoṣo ni O le ràn wọn lọwọ. Bi wọn ti mọ ara wọn ni ẹlẹbi niwaju Oluwa, ti wọn si n beere fun iranlọwọ ni alaafia Ọrun n sọkalẹ si ọkàn wọn. Wọn mọ pe a ti dariji wọn, a si ti gbà wọ́n là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn.

Idahun ti Jesu fun obinrin yii fi han an pe ko yẹ fun iranlọwọ yii, nitori ki i ṣe Ọmọ Israẹli, a kò si ti i rán Ihinrere si awọn ẹlomiran. O wi pe kò ni tọna lati fi ounjẹ awọn ọmọ bọ́ aja. Ohun ti Oluwa wi yé obinrin yii, inu ko si bi i nitori Jesu fi wé ajá. Inu maa n tete bi awọn miiran nipa gbigba ọrọ sodi, wọn yoo si lọ pẹlu igbọgbẹ ọkàn. Nipa ṣiṣe eyi, wọn yoo padanu ibukun ti Ọlọrun fẹ fi fun wọn gẹgẹ bi a ki ba ti wo ọmọbinrin naa sàn bi o ba ṣe pe iya yii binu lọ.

Obinrin yii ko fẹ gba ẹtọ awọn Ju lọwọ wọn, gẹgẹ bi idahun rẹ̀ ti fihan. O sọ fun Oluwa pe oun n fẹ eyi ti o ba ṣẹ̀kù silẹ, tabi eyi ti awọn miiran kọ silẹ. Kó si ẹni ti yoo kọ pe ki a fi èérún bọ́ ajá. Ninu ipo irẹlẹ rẹ̀, o beere bi oun ba le gba diẹ ninu iranlọwọ Rẹ̀ yii ti awọn miiran ti kuna lati gbà.

**Ere Igbagbọ**

Ki i ṣe ijiyan rẹ̀ ni o mu ki Oluwa ṣaanu fun un: ṣugbọn igbagbọ rẹ̀ ni o mu ibukun iwosan wa fun ọmọbinrin rẹ̀. Nipa awiyannu adura rẹ̀ o fi han pe o ni igbagbọ. Jesu wi pe igbagbọ́ nla ni ti obinrin yii, ati pe a mu ibeere rẹ̀ ṣẹ.

Nitori obinrin yii lọ sọdọ Jesu, o si gbadura pẹlu igbagbọ́ a wo ọmọbinrin rẹ̀ sàn lẹsẹkẹsẹ. Aisan naa lọ; a si mu iwuwo, aniyan ati aibalẹ aya kuro ninu ọkàn obinrin yii. Lai si aniani, nigba ti o ba tun ro ibasọrọ rẹ̀ pẹlu Jesu yoo mọ pe oun ki bá ti ri ibeere oun gba bi oun ba ti tete ju ọwọ́ silẹ. Bawo ni inu rẹ yoo ti dun to pe oun ni ipinnu ati pe oun beere titi a fi dahun ẹbẹ oun.

Awọn miiran maa n ju ọwọ silẹ nigba ti o ku diẹ ki wọn ri ibukun gbà. Wọn le ma wa Ọlọrun fun iwosan agọ ara wọn, tabi ki wọn maa wa Ọlọrun fun igbala tabi ọkan ninu awọn iriri Onigbagbọ. Boya Ọlọrun dán igbagbọ wọn wò, ṣugbọn wọn a lọ lai ri idahun adura wọn gba, dipo ki wọn gbadura siwaju diẹ si i. Ẹ jẹ ki a pinnu lati dabi obinrin yii ti o fi igbagbọ rẹ̀ ninu Oluwa hàn nipa iforiti, ipinnu ati adura awiyannu rẹ̀.

**A Yin Ọlọrun Logo**

Lẹyin naa Jesu lọ si ori oke kan lẹba Okun Galili, ọpọlọpọ eniyan si tọ Ọ wa fun iwosan. Oniruuru ọna ni a gba fi n pọ́n wọn loju, o si wuwo lọpọlọpọ pẹlu. Ko si iranlọwọ fun awọn ti ko le riran, ti ko le gbọran, ti ko le sọrọ ati awọn ti ko le rin -- kò si iranlọwọ, bi ko ṣe ninu Jesu. Ko si ya ni lẹnu nigba naa pe awọn eniyan yin Ọlọrun logo nigba ti wọn ri awọn alaisan wọnyii ti wọn n riran, ti wọn n gbọran, ti wọn n sọrọ, ti wọn si n rìn laṣẹ Jesu.

**"Iwọ Ṣí"**

Ninu Marku, ori keje a kà nipa ọkunrin kan ti ko le sọrọ ketekete, ti ko si le gbọran. Jesu mu un kuro laaarin ijọ eniyan ki wọn ba le nikan da wa nibi kan. O fi ọwọ kan eti ati ahọn ọkunrin yii, ibi ti a n pọ́n loju ni agọ ara rẹ̀. Jesu gbe oju soke si Ọrun, O si gbadura pe, "Iwọ ṣí." Loju kan naa ọkunrin yii gbọran o si sọrọ. Ẹnu ya awọn eniyan si iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe. Ẹnu kò ya obinrin ara Sirofenikia nitori o ni igbagbọ́, o ni ireti pe Oluwa yoo wo ọmọbinrin oun sàn.

A ki i dẹkún lati maa yin Ọlọrun logo fun iṣẹ iyanu ti O maa n ṣe lonii, ṣugbọn ẹnu ki i yà wa si awọn iṣẹ iyanu wọnyii. Ilọpo meji iwosan ni o wà ninu Ẹjẹ Jesu, iwosan fun aisan ti ara ati ti ẹmi. O le wosan, O si n wosan sibẹ gẹgẹ bi O ti n gba awọn ti o nu là (Isaiah 53:5). Nigba ti awọn eniyan Ọlọrun ba n ṣaisan ti a si n pọn wọn loju, a pa a laṣẹ fun wọn lati gbẹkẹ le Oluwa. Oun yoo si gbe wọn dide nipa adura igbagbọ́ (Jakọbu 5:14, 15). "Emi li OLUWA ti o mu ọ lara dá" (Ẹksodu 15:26). Ọpọlọpọ ni ipọnju olododo, ṣugbọn OLUWA gbà a ninu wọn gbogbo" (Orin Dafidi 34:19).

**Aditi nipa ti Ẹmi**

Ọpọlọpọ eniyan ni o wà ninu aye lonii ti wọn dabi ọkunrin yii. Aditi ati ayadi ni wọn nipa ti ẹmi. Wọn ki i gbọ Ọrọ Ọlọrun bẹẹ ni wọn ki i sọrọ nipa Ọlọrun ati ibukun Rẹ. Wọn le fi eti ode ara gbọ́, ṣugbọn wọn ki i feti si ohùn Ọlọrun. O daju pe wọn ko le sọrọ iyin ati ọla Ọlọrun titi di igba ti wọn ba gbọ nipa wọn, ti wọn ba si fiyesi ohun ti wọn gbọ́.

Awọn miiran wa ti wọn maa n lọ si ile-isin ti wọn si n gbọ iwaasu, ṣugbọn wọn ko fi eti ẹmi gbọ Ọrọ Ọlọrun. Eṣu ọta wọn ẹmi ti di eti wọn si Ihinrere. Ko si atunṣe fun aditi nipa ti ẹmi, ṣugbọn Jesu le wosan, O si le gbala. Wọn ni lati lọ sọdọ Jesu, ki wọn wà pẹlu Rẹ nikan, ki Oun le la eti wọn, ki wọn ba le gbọ otitọ Ihinrere. Nigba naa ni iyin Ọlọrun yoo maa jade lati ẹnu wọn, nitori a o tú ahọ́n wọn pẹlu. Ẹri wọn yoo jẹ́; "O ṣe ohun gbogbo daradara" Marku 7:37).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti obinrin naa kigbe pe Jesu?
2. Ki ni ṣe ti o pe E ni "ọmọ Dafidi?"
3. Nitori o tẹra mọ adura gbigba, ki ni o ri gbà?
4. Bawo ni o ti gba Jesu lakoko tó, ki O to wo ọmọbinrin naa sàn?
5. Iru aisan wo ni awọn miiran ti wọn tọ Jesu wa fun iwosan ní?
6. Ki ni ṣe ti ẹnu ya awọn eniyan wọnyii?
7. Ki ni awọn eniyan naa ṣe lẹyin ti Jesu ti wo awọn alarun wọnyii sàn?
8. Ki ni eniyan gbọdọ ṣe nigba ti o ba lọ sọdọ Jesu fun iwosan?